## Ọ̀nà sí ètò ìṣe orílẹ̀ èdè lòdì sí ẹlẹyẹmaya fún ìkànsí ará ìlú ni Ireland 2021

**Ìfáàrà**

**Ìgbìmọ̀ tó ń ṣe lòdì sí ẹlẹ̀yámẹ̀yá àti ìròyìn wọn**

Ìgbìmọ̀ tó ń ṣe lòdì sí ẹlẹ́yàmẹ̀yà ti orílẹ̀ èdè (National Anti-Racism Committee) jẹ igbimọ ti o dádúró ti ìjọba gbé kalẹ̀ ní ọdun 2020 láti ya àgbékalẹ̀ ìgbésẹ̀ ìṣe ti orílẹ̀ èdè ti o lodi si ẹlẹ́yàmẹ̀yà fún Ireland. O le ri ìsọdi ọmọ ẹgbẹ́ wa àti awọn ìlànà à ń tẹ̀ẹ́lé nihin.

Ni ibamu pẹlu awọn liana à ń tẹ̀lé wa, a ti gbé èsì àwa ìgbímọ̀ adelé fún Mínísítà fún àwọn ọmọdé,dọ́gbandọ́gba,àìlera, ìmúgòkè àti ọ̀dọ́ (Minister for Children, Equality, Disability, Integration and Youth) ní osù kọ́kànlá 2020. Esi naa fi àwọn èrò tí a ní ibẹrẹ hàn ati àwọn ètò wa fún ìdàgbásoké ètò ìṣe fún orílẹ̀ èdè lòdì sí ẹlẹ́lẹ̀yàmẹ̀yá. O le rí àbọ̀ ìgbìmọ̀ adelé nihin.

Kìkànsí pẹ̀lú àwọn àkójọpọ̀ onígbọ̀wọ́ àtí àwọn ará ìlú jẹ́ ọ̀kan Pàtàkì lára iṣẹ́ wa. Ìkànsí yí fún olúkúlùkù ní ànfààní láti sọ èrò tiwọn lórí bí a ti ṣe le gbógun ti ẹlẹ́yàmẹ̀yà àti gbogbo irú rẹ ni Ireland loni.

A ti múra ìwé ìkànsíni yi láti ṣàlàyé ohun tí kíkànsí náà túmọ̀ sí àti láti yànàná àwọn ọ̀nà tí a o ti tẹ́wọ́ gba èròǹgbà àti àbá wọn.

**Àwọn èròǹgbà rẹ ṣe pàtàkì ní rírànwálọ́wọ́ láti ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ọ̀nà tó múyánlórí láti gbógun ti ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní Ireland.**

**Kínni ẹlẹ́yàmẹ̀yà?**

Ninu abọ awa igbimọ adelé, a gbé àwọn òye wọ̀nyí nípa ẹlẹ́yàmẹ̀yà kalẹ̀ láti ṣe atọ́kùn fún iṣẹ́ wa:

> [Ẹlẹ́yàmẹ̀yà jẹ́]… agbára tí àwọn ìyàtọ̀ ṣàgbékalẹ̀ nínú àwọn àlàkalẹ̀ àti àwọn ètò ilé iṣẹ́, ìmúlò, àti àwọn àṣà ìbílẹ̀, èyí tí ó ní ipa yáyanisọ́tọ̀ tàbí ṣíṣe ẹlẹ́yàmẹ̀mẹ̀yà lodì sí ẹnìkọ̀ọ̀kan tàbí àwọn àkójọpọ̀ ènìyàn, èyí tó dá lórí ìdánimọ̀ wọn, gẹ́gẹ́ bi a ti yànnàná rẹ̀ ní àròkọ akọ́kọ́ ti àpéjọpọ̀ orílọ̀ èdè àgbáyé fún ìmúkúrò ìdẹ́yẹsí èyà kan (ICERD), èyí tó pèsè fún:
> ‘...ofin “ìkóríra ẹ̀yà” yóò túmọ̀ sí ìyàsọ́tọ̀, ìyọnikúrò, híhánimọ́, tàbí ojúṣàjú tó dálórí ẹ̀yà, àwọ̀,ìran, tàbí òrílẹ̀ èdè orísun ẹ̀yà tí ó ní èrèdí tàbí ipá láti fagilé tàbí tàbùkù ìdánimọ̀, ìgbádùn tábí ìdárayá, tí ó dúró lórí ẹsẹ dọ́gbandọ́gba, ti àwọn ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn àti òmìnra òsèlú, ìse, ọrọ̀ ajé, àwùjọ, àṣà àti èyíkéyí àyè míràn ní àwùjọ’.[1]

---

[1] Ìròyìn ìgbìmọ̀ adelé lòdì sí ẹlẹ́yàmẹ̀yà, 2020, 3.

A dá onírurú ìyapa ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ mọ̀ láàrín ẹlẹ́yàmẹ̀yà àti àwọn irú ìnilára míràn tó dá lórí ẹ̀yà akọ àti abo, ìbálòpọ̀, àìlera, àti àwọn àyídáyidà ọrọ̀ ajé- àti pé àwọn obìnrin, àwọn ọmọdé àti àwọn okùnrin ní ìrírí àwọn onírurú ẹlẹ́yàmẹ̀yà tó ṣọ̀tọ̀ọ̀tọ̀.

Òye náà tí a ti gbà wọlé jẹ́ èyí tó wà láàyè, kí kọ́ lórí àwọn èròngbà òfin àwọn orílẹ̀ èdè àgbáyé ati awọn ojúṣe bákan náà ni ti EU ati ìṣòfin ilẹ̀ Irish.

Ẹlẹ́yàmẹ̀yà jẹ ìsòro tí o farahan lẹ́sẹlẹ́sẹ ni orisirisi ọ̀ná ní àwùjọ tí ó sì ti ní àwọn ipá lórí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbé ayé àwọn ènìyàn. Ẹlẹ́yàmẹ̀yà jẹ ifibọ ni awọn ọ̀nà; o ti han ati pe o ti di àtúndá ní àwọn ilé ẹ̀kọ́, àwọn ìṣe, àwọn àlàkalẹ̀ àti àwọn àṣà; àti nípasẹ̀ wọn ó ti ní ipa tí ó yanisọ́tọ̀ tàbí tóń ṣe ẹlẹ́yàmẹ̀yà lòdì sí olúkúlùkù tàbi àwọn àkójọpọ̀, lórí ìran tàbí ẹ̀yà (tí ó pẹ̀lú orílẹ̀ èdè ati ẹgbẹ awujọ awọn arinrin ajo).

**Ẹ̀lẹ́yàmẹ̀yà jẹ òtítọ́ ní Ireland. A ní lò ètò orílẹ̀ èdè tó ní ìgbésẹ̀ tó kún àti èyí tó múnádóko láti gbógun tì í.**

Ẹlẹ́yàmẹ̀yà jẹ́ òtítọ́ ní Ireland. ẹ̀rí tó dájú tó sì ń lọ lọ́wọ́lọ́wọ́ fihàn pé ó ti gbẹ̀rẹ̀gẹ̀jigẹ̀ ní gbogbo ipele láwùjọ àti pé onírurú àwùjọ ni ó ti ní ìrírí rẹ̀. COvid ti túnbọ̀ tú àṣírí ẹlẹ́yàmẹ̀yà- pẹ̀lú ipa tó yàtọ̀ fún àwọn aṣíkiri àti àwọn àwùjọ míràn tí ó jẹ́ àfojúsùn ìdẹ́yẹsí ẹlẹ́yàmẹ̀yà.

Gbígba àwọn ẹ̀rí tó wúwo ní bí àwọn ọdún díẹ̀ sẹ́yìn pé ẹlẹ́yàmẹ̀yà wà, a mọ̀ pé a gbọ́dọ̀ gbé ìgbésẹ̀ nísinsìnyí. Láti ìgbà tí ìgbésẹ̀ ètò orílẹ̀ èdè lòdì sí ẹlẹ́yàmẹ̀yà tó wáyé tẹ́lẹ̀ tó parí ní 2008, àwọn àgbáríjọ ẹgbẹ́ ìlú tí ń béèrè fún àtúnṣe àfojúsùn orílẹ̀ èdè, àlàkalẹ̀ tí aṣe àtúnṣe sí nínú àgbéyẹ̀wò tó kẹ́hìn ní Ireland nípasẹ̀ ìgbìmọ̀ UN tó wà fún ìmúkúrò ẹlẹ́yàmẹ̀yà (CERD) ní 2019. Àjọ àwọn ẹ̀tọ́ ọmọ ènìyàn àti dídọ́gba ní Irish (Irish Human Rights and Equality Commission) bákan náà ti pè fún ìfilọ́lẹ̀ ìgbésẹ̀ ètò ìdàgbàsókè tuntun fún orílẹ̀ èdè.
Òfin Ireland ní lọ́wọ́lọ́wọ́ yìí ń ṣe lòdì sí ẹlẹ́yàmẹ̀yà àti pé ọ̀rọ̀ ìkórira jẹ́ èyí tí kò bófin mu bákan náà. Gbogbo àwùjọ ní ilẹ̀ Irish ni ó ní ojúṣe láti gbé ìgbésẹ̀ tó gbúpọn láti pa ẹlẹ́yàmẹ̀yà run (tódá lórí orílẹ̀ iran) ní ìdí iṣẹ́ wọn. Ìgbéláruge dọ́gbandọ́gba àti kíkà kún àwọn ẹ̀yà tí ó kéré jẹ́ ọ̀kan Pàtàkì lára àwọn ọ̀nà tí wọn ti dárúkọ láàrín ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀ka ìjọba àti àwọn ètò ìlú. Àwọn ọ̀nà láti ṣẹ́gun ẹlẹ́yàmẹ̀yà wà nínú ète fún ìdàpọ̀ mọ́n àwùjọ àwọn aṣíkiri àti arìnrìnàjò ti orílẹ̀ èdè àti ète ìfàyègbani Roma . Onírurú àwọn àtúntò ni ó tiń wáyé lọ́wọ́lọ́wọ́ yóò jẹ́ Pàtàkì ní ríró àwọn ènìyàn lágbára lábẹ́ àwọn òfin lòdì sí ẹlẹ́yàmẹ̀yà. Àwọn wọ̀nyí wà lára àbá ìṣòfin ìlùfin ìkórira àti ìbára ẹnisọ̀rọ̀ orí ayélujára. Àwọn àtúntò bíi àwọn wọ̀nyí n ṣàfihàn àmì tó lágbára pé àwùjọ Irish kò ní fi àyè gba kí àwọn ẹ̀yà kékeré máa jìyà lábẹ́ ẹlẹ́yàmẹ̀yà Kankan.
Ẹ̀wẹ̀, ẹlẹ́yàmẹ̀yà àti ìya ìran sọ́tọ̀ ń tẹ̀síwájú ní Ireland bó tilẹ̀ jẹ́ pé òfin lòdì síi. Àwọn òfin àti àlàkalẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́ yìí kò tó bákan náà ni àwọn àlàfo ṣì wà.
Ìgbésẹ̀ ìṣe ti orílẹ̀ èdè náà yóò pèsè ọ̀nà tí yóò sàgbékalẹ̀ àwọn òduwọ̀n àti òfin tí ó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ ní ìlànà tó gbòòrò fún àwọn ìgbésẹ̀ tó le mú kí iṣẹ́ rẹ múnádóko.
Bákan náà ni yóò ṣe àfihàn àwọn ìgbésẹ̀ àti ìpilẹ̀ṣẹ̀ tuntun làti dojúkọ àwọn ìpènijà tí ó ti wà àti àwọn èyí tí ó ń jẹyọ. Ní mímú àwọn ìgbésẹ̀ àti àwọn ìpilẹ̀ṣẹ̀ tùntùn wọ̀nyí dàgbàsokè, a o

kíyèsí pé ẹlẹ́yàmẹ̀yà ti darapọ̀ pẹ̀lú àwọn àìdọ́gba míràn àti ìdẹ́yẹsí ẹ̀yà ní àwọn àyè míràn. Fún àpẹẹrẹ ìmọ̀ akọ àti abo àti àìlera.

## Níní àkọsílẹ̀  dídọ́gba tó dára ṣe pàtàkì láti dojúkọ ẹlẹ́yàmẹ̀yà

Bíbójútó dọ́gbandọ́gba ẹ̀yà jẹ́ kọ́kọ́rọ́ kan gbòógì fún sísíṣọlọ́jú yíya ìran kan sọ́tọ̀ tí ó gbòde kan àti ipa tí ó ní lórí ayé wa.
Ó ṣe kókó sí ìdàgbàsokè tó múnádóko. Àwọn àgbèyẹ́wò ajà fún ẹ̀tọ́ àwọn ọmọ ènìyàn ni àgbáyé ti ṣe àtẹnumọ́ ìpe wọn fún Ireland láti tẹ́wọ́gba ọ̀nà tí kò yẹsẹ̀ fún gbígba ohun tó yẹ kámọ̀ nípa àwọn ẹ̀yà tó yapa láti ọwọ́ àwọn olùpèsè isẹ́ fún àwọn ará ìlú àti àwọn míràn.
Àbọ̀ àwa ìgbìmọ̀ adelé dá èyí mọ̀ gẹ́gẹ́bí àbá tó ṣe Pàtàkì jùlọ. Ìgbésẹ̀  amúsẹ́ yá ti orílẹ̀ èdè yóò túnbọ̀  yànànà àwọn àlàfo tí ó wà nínú kíkó ohun tó yẹ kámọ̀ jọ àti lílò rè, àti ṣíṣàgbéyẹ̀wò irú àwọn àyípadà tí ó le rànwálọ́wọ́ láti ṣàmúlò ohun tó yẹ kámọ̀ dáradára ní jíjà tako ẹlẹ́yàmẹ̀yà.

**Sí ìgbésẹ̀ ètò orílẹ̀ èdè lòdì sí ẹlẹ́yàmẹ̀yà fún ireland**

Ó ṣe Pàtàkì pé kí ètò náà fi ẹsẹ̀ rinlẹ̀ nínú ìfarajì sí àwọn iyì ẹ̀tọ́ ọmọ ènìyàn, ìjọba tiwan tiwa àti àgbékalẹ̀ òfin. Àwọn iyi wọ̀nyí gbọ́dọ̀ ṣe àpèjúwe ọ̀nà àti múni mo àwọn ìgbésẹ̀ àwùjọ Irish ní dídojú ìjà kọ ẹlẹ́yàmẹ̀yà.
Gẹ́gẹ́ bí a ti kọ́ sínú ìròyìn ìgbìmọ̀ adelé, iṣẹ́ wa wà ní ìbámu pẹ̀lú isẹ́ tó dára jùlọ èyí tó dá lórí ọ̀nà àti àkópọ̀ tí ó wà nínú ìgbésẹ̀ ètò tí ó lòdì sí ẹlẹ́yàmẹ̀yà orílẹ̀ èdè bí a a ti gbe kalè ní ìtọ́nisọ́nà tó wúlò sí ìdàgbàsokè àwọn ètò ìsẹ ti orílẹ̀ èdè lòdì sí ìdẹ́yẹsí ẹlẹ̀yàmẹ̀yà tí a gbéjáde láti ilé iṣẹ́ àjọ àpapọ̀ àgbáyé fún ẹ̀tọ́ ọmọ àwọn ènìyàn

Bákan náà iṣẹ́ wa ní ìbámu pẹ̀lú ètò ìṣe EU  lòdì sí ẹlẹ́yàmẹ̀yà(2020-25), èyí tí ó ṣe àfihàn ìlànà UN.

Ní ìbámu liana UN, ań fẹ́ láti ṣe àgbédìde ètò ìṣe orílè èdè lòdì sí ẹlẹ́yàmẹ̀yà ìyẹn pé:

- *Ó dá lórí  àwọn òpágun ẹ̀tọ́  ọmọ ènìyàn*
- *Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ tó gbòòrò*
- *Ìdáwọ́lé orílẹ̀ èdè*
- *Ìgbésẹ̀*
- *ìwé ará ìlú*
- *Ètò tó ń tẹ̀ síwájú*
- *Pẹ̀lú ìwọ̀n agbaye.*[2]

[2] *Mímú ìdàgbàsokè  ìgbésẹ̀ ìṣe ti àwọn orílẹ̀ èdè lòdì sí ìdẹ́yẹsí ẹ̀yà ẹni: títọ́nisọ́nà tó wúlò*, UN OHCR 2014, 3.

## Ní ìkòríta yìí, a fẹ́ gbọ́ àwọn èròǹgbà yín

Kíkọ́ lórí ọ̀ye ẹlẹ́yàmẹ̀yà àti àwọn agbègbè tí ó kàn tí a kọ jáde nínú ìròyìn ìgbìmọ̀ adelé, àti ìfitóni létí ìkànsíni yìí, ìgbésẹ̀ ètò orílẹ̀ èdè yóò di fífi ránṣẹ́ sí gbogbo ẹ̀ka ìjọba àti ilé iṣẹ́, àwọn aláṣẹ, àwọn ìdásílẹ̀, àti àwọn àkójopọ̀- ilé iṣẹ́ ìjọba, ti aládáni àti ti àtinúwá - èyí tó ní ojúṣe láti dojúkọ ẹlẹ́yàmẹ̀yà tàbi èyítí iṣẹ́ rẹ̀ ṣe Pàtàkì. Àfojúsùn ìgbésẹ̀ ètò orílẹ̀ èdè yóò wà lára ilé iṣẹ́ ìgbéròhìn sáfẹ́fẹ́, ti ìṣẹ̀ṣe àti ti ìgbàlódé. Yóò ní àwọn ètò tí yóò gbé ẹ̀tọ́ àti dọ́gba ń dọ́gba gbogbo ènìyàn tí ó ń gbé ní Ireland láruge.

Láti ràn wá lọ́wọ́ fún títo ìkànsíni wa, a ti dábá ọ̀pọ̀lọpọ̀ àkòrí tí ó ṣàfihàn àwọn ọ̀ràn tí a ti ṣàwárí nínú ìróyìn àwa ìgbìmọ̀ adelé. Jọ̀wọ́ a ń fí dá ọ lójú wípé a kò ítì i yan àwọn àkòrí wọ̀nyí nítorípé a rò wípé agbègbè yí nìkan ní ẹlẹ́yàmẹ̀yà ti ń wáyé, tàbí pé àwọn àkòrí yìí nìkan ni ó nílò ìdojúkọ nínú ìgbésẹ̀ ètò òrílẹ̀ èdè. Wọ́n wulẹ̀
Dábá wọn láti ru ìjírórò sókè lásán ni àti pé kí ó lè ràn wá lọ́wọ́ láti to ìkànsíni náà. A sì ń làkàkà láti gbọ́ àwọn èròńgbà yín lórí ọ̀ràn kọ́ràn míràn tí ẹ́ lérò wípé ó yẹ kí a ṣàgbéyẹ̀wò ní ètò ìdàgbàsókè náà.
Ati pèsè ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìbéèrè lórí ọ̀kọ̀kan àkòrí tí yóò rànwálọ́wọ́ láti ru ìjíròrò sokè. O le rí àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ìsàlẹ̀ yóò se ìrànwọ́ láti ṣàgbékalè ìkópa yín sí ìkànsíni náà. Sùgbọ́n jọ̀wọ́ o ní òmìnira láti sọ èròńgbà rẹ lórí àwọn ọ̀ràn wọ̀nyí láì kàn sí àwọn ìbéèrè, àti/tàbí láti sọ èròńgbà rẹ lórí àwọn ọ̀ràn míran tí a kò mẹ́nubà nínú ìwé yìí. Bákan náà a mọ̀ pé óṣeéṣe kí ọ̀pọ̀lọp ìbòjú wà láàrín àwọn àkòrí yìí.

| | |
|---|---|
| **Àkòrí 1:** | **Rírí ìdájọ́ òdodo** |
| **Àkòrí 2:** | **Gbogbo irú ilé iṣẹ́ ìgbóhùn sáfẹ́fẹ́ àti àwọn ìbánisọ̀rọ̀, pẹ̀lú àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ tuntun** |
| **Àkòrí 3:** | **Ìgbani síṣẹ́, ẹ̀kọ́, ìlera, àti ilé gbígbé** |
| **Àkòrí 4:** | **Ìfàyègbani àti kíkópa** |

1. ***Rírí ìdájọ́ òdodo***

Àkòrí yí wà lára dídojúkọ ẹlẹ́yàmẹ̀yà nípasẹ̀ àwọn aláṣẹ agbófinró, pẹ̀lú ọ̀ràn ẹ̀sùn ṣíṣètò, àìkúnjú òṣùwọ̀n-rírò̀yìn àti àwọn àtúnṣe míràn

- Kínni ìrànlọ́wọ́ tí o fẹ́ láti rí fún àwọn tó faragbá nínú ìṣẹ̀lẹ̀ ẹlẹ́yàmẹ̀yà?
- Irú ìgbésẹ̀ wo ní ó múnádóko láti mú àwọn ìdènà sí ìdájọ́ fún àwọn afaragbá nínú ìṣẹ̀lẹ̀ ẹlẹ́yàmẹ̀yà?
- Kíni ìgbésẹ̀ tí a le gbà láti lòdì sí ìdẹ́yẹsí láti ọ̀dọ̀ àwọn agbófinró?
- Ṣé o rò pé ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní ipa lórí àwọn tí wọ́n fi pańpẹ́ òfin mú tàbí àwọn tí wọ́n fi ẹ̀sùn ọ̀daràǹkàn nílé ẹjọ́ tí ó bá ríbẹ̀, báwo ni a ṣe le dojú kọ?
- Ṣé o rò pé ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní ipa lórí àwọn tí a dálẹ́ bi tàbí ènìyàn tí wọ́n fisí ẹ̀wọ̀n ní ilé ẹjọ́, tí ó bá rí bẹ́ẹ̀ báwo ni a ṣe le dojú kọ ọ́?

- Ṣé o rò pé ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní ipa lórí ètò ìdájọ́ àti àwọn ilé ẹjọ́ náà, tí ó bá rí bẹ́ ẹ̀, irú ìgbésẹ̀ wo ni a nílò láti gbé?
- Ṣé àwọn ọ̀ràn kan wà tí ó sopọ̀ mọ́ ẹlẹ́yàmẹ̀yà àti ìdá akọ àti abo mọ̀ àti rírí ìdájọ́ òdodo gbà?

2. ***Gbogbo irú ilé iṣẹ́ ìgbóhù sáfẹ́fẹ́ àti ìbára ẹni sọ̀rọ̀, pẹ̀lú àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ ìgbàlódé***

Àkòrí yìí pẹ̀lú ìwé ìròyìn àti ilé iṣẹ́ ìròyìn ìbílẹ̀ àti ilé iṣẹ́ ìgbéròyìnjádè àti ti ìgbóhùnsáfẹ́fẹ́ bákan náà ní orí ẹ̀rọ ayélujára àti àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ tuntun.

- Irú ìgbésẹ̀ wo ni o máa dábá kí a gbé dojúkọ ẹlẹ́yàmẹ̀yà nínú ìgbóhùnsáfẹ́fẹ́ tuntun àti ti ìbílẹ̀?
- Irú ìgbésẹ̀ wo ni o rò pé yóò rànwálọ́wọ́ láti mú ìgbóhùnsáfẹ́fẹ́ àti ìgbéròhìn jáde ṣe aṣojú dáradára ní gbogbo ipele àwọn ènìyàn tí ó ń gbé ní Ireland?
- Kínni àwọn ìpènijà tí ìmọ̀ ẹ̀rọ ń dojúju kọ tí a bá n sọ̀rọ̀ nípa ẹlẹ́yàmẹ̀yà?
- Ǹjẹ́ o ní àǹfààní Kankan tí ìmọ̀ ẹ̀rọ tuntun ní fún ìró lágbára ìjà lòdì sí ẹlẹ́yàmẹ̀yà?
- Kínni ìgbésẹ̀ tí ó yẹ ní gbígbé láti ilé iṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ tí yóò ràn wálọ́wọ́ láti dojú ìjà kọ ẹlẹ́yàmẹ̀yà?
- Kínni ipá tí fífi òfin sí ilé iṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ le kó ní dídojúìjàkọ ẹlẹ́yàmẹ̀yà?

3. ***Ìgbanisíṣẹ́, Ẹ̀kọ, Ìlera, àti Ilé gbígbé***

Àwọn wọ̀nyí ni ẹ̀ka tó ṣe kókó nínú ètò ọrọ̀ ajé àti igbé ayé níbití ati nilo awọn igbesẹ fun ẹkunrẹrẹ atilẹyin fún fífàyègbà àti kíkópa àwọn àkójọpọ̀ ènìyàn tí ó ń ní ìrírí ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní àwùjọ àti ètò ọrọ̀ ajé. Ẹ̀yí le wà lára dídojúkọ ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní ibi iṣẹ́; rírídájú wípé iṣé ìjọba ni a ṣàgbékalẹ̀ tí a sì jẹ́ pẹ̀lú kíkó gbogbo ènìyàn mọ́ra; àti àwọn ọ̀nà láti kojú àìdọ́gba ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní rírí àyè sí, kíkópa nínú àti àbájáde láti ẹ̀kọ́, ìlera, iṣẹ́, ilé gbígbé.

- Báwo ni o ṣe fẹ́ kí a kọjú ẹlẹ́yàmẹ̀yà ẹ̀ka ètò ẹ̀kọ́?
- Báwo ni o ṣe le rí pé dọ́gbandọ́gba àwọn ọmọ kékèké dájú tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa rírí iṣẹ́ sí àwọn iṣẹ́?
- Kínni àwọn ìgbésè tí o fẹ́ láti rí kí a gbé ní ẹ̀ka ìlera láti yanjú àìdọ́gba tó dá lórí ẹlẹ́yàmẹ̀yà?
- Kínni àwọn òṣùwọ̀n tó máa ṣèrànlọ́wọ́ láti yanjú ẹlẹ́yàmẹ̀yà ni rírí sí ilé gbígbé?
- Kínni ìdásílẹ̀ ati àwọn ìgbésẹ̀ tí o máa fẹ́ rí kí a gbé dojúkọ ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní rírí àyè si ìgbanisíṣẹ́?
- Ṣé àwọn ẹ̀ka òṣìṣẹ́ kan gbòógì wà níbití a ti ní láti ṣe àgbélekè ìdojúkọ ẹlẹ́yàmẹ̀yà?
- Kínni ìdánilẹ́kọ́ àti àfikún àtìlẹhìn tí ó le ṣe ìrànlọ́wọ́ láti dojúkọ ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní ibi iṣẹ́?
- Kínni àwọn òṣùwọ̀n tí a le ṣàfihàn fún ìgbélárugẹ ìgbanisíṣẹ́ àti ìfini sára ní ọjà òṣìṣẹ́, bákannáà ní yíyanjú àwọn ohun tó ń sokùnfà ìdẹ́yẹsíni?

4. ***Fífàyègbà àti kíkópa***

Àkòrí yí wà lára ipa tí ẹ̀kọ́ àti ìmòye le kó ní gbogbo ẹ̀ka láti dojúkọ àwọn ìwà àti ìṣesí afẹ̀yàbúni. Ẹ̀yí le wà lára òṣùwọ̀n láti mú ẹ̀kọ́ kíkọ́ nípa ìyàtọ̀ àti ẹlẹ́yàmẹ̀yà wuyì nínú ẹ̀kọ́

kíkọ́, títú ìtàn kọ láti fàyè gba àwọn ẹgbẹ́ àti àwọn apá míràn tí a ti fojù fòdà lọ́wọ́lọ́wọ́, bákan náà ní gbígbéga àkíyèsí àwọn ará ìlú.

Lábẹ́ àkòrí yìí ao fẹ́ láti yanjù àwọn ìdènà sí ènìyàn láti àwọn ẹ̀ya tó kéré tí ó ń kópa ní òṣèlú àwa ara wa tí wọ́n sì ń kópa nínú ìdìbò ní ìjọba ìbílẹ̀ àti ti orílẹ̀ èdè.
A o tún ṣàgbéyẹ̀wò àwọn ètọ́ àyè rírí sí àyèkayè tàbí iṣẹ́ tí àwọn ìlú gbèrò làti lò, àwọn bíi ìrìnà,ilé ìgbafẹ́,àwọn ilé ìtàjà ohun jíjẹ, ilé ìtajà ohun mímu, àwọn sinimọ́n, àwọn ohun ìdárayá, àwọn ọgbà atiàwọn amáyérọrùn.

- Kínni ìfilọ́lẹ̀ tí o rò pé ó le gbé ìlanilọ́yẹ̀ ará ìlú sókè nípa ìdẹ́yẹsí ẹlẹ́yàmẹ̀yà pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ láti dojúkọ ìpìlẹ̀ ẹlẹ́yàmẹ̀yà?
- Báwo ni a ṣe le mú àwọn ìdènà sí ìfàyègbani àwùjọ kékeré àti kíkópa àwọn tí wọ́n kò ní aṣojú tó tó àti àwọn ẹgbẹ́ tí kò ní ànfààní?
- Báwo ni a ṣe le ri dájú wipe afi àyègba àwọn tí a ṣátì julọ?
- Kínni àwọn ìfilọ́lẹ̀ tó máá ṣe ìrànlọ́wọ́ láti ri dájú pé ìlànà ìlu fi ẹlẹ́yàmẹ̀yà tíó ń wáyé lẹ́sẹẹsẹ tí àwọn ẹ̀yà tí wọ́n dẹ́yẹsí i wọn ń dojúkọ sí ìṣiró?
- Kínni ìgbésẹ̀ tí o má dábá láti ṣàfikún ẹgbẹ́ àwọn ènìyàn tí ó wá láti ẹ̀yà tó kéré tí ó ń kópa tí ó sì ń dúró ní ìjọba ìbílẹ̀ àti ètò ìdìbò orílẹ̀ èdè?
- Kínni àwọn ìgbésẹ̀ tí a nílò láti ri pé ètò òṣèlú, àwọn ọ̀nà àti kíkópa jẹ́ èyí tó lòdì sí ẹlẹ́yàmẹ̀yà?
- Kínni ìgbésẹ̀ tí a ní láti gbé láti yanjú ẹlẹ́yàmẹ̀yà nínú eré ìdárayá? Kínni ìgbésẹ̀ tó dára to le mú kí èyí dára si?
- Kínni ìgbésẹ̀ tí a nílò láti gbé kí a lè gbé àkíyèsí ga kí a sì yanjú ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní ìṣe àti àṣà? Kínni ìgbésẹ̀ tó dára tó le mú kí èyí dára si?
- Kínni ìgbésẹ̀ tí a nílò láti gbé láti ṣàgbéláruge oríṣiríṣi àṣà àti kíkópa àwọn ará ìlú?

A kí ọ káàbọ̀ láti fún wa ní èròngbà tìrẹ lórí ohunkóhun tí o rò pé ó yẹsí ìdàgbàsokè ètò ìṣe ti orílẹ̀ èdè tako ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní Ireland. Àwọn ìbéèrè gbogboògbò tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yi lè ṣe ìrànlọ́wọ́.

**Àwọn ìbéèrè gbogboògbò**

- Kínni o rí gẹ́gẹ́ bí ìṣòro tó ṣe pàtàkì jùlọ tí ó ń kojú àwọn ẹ̀yà kékeré?
- Kínni ìfilọ́lẹ̀ tí o rò pé yóò yanjú àwọn àlàfo tó wà ní kíkó ohun tó yẹ kámọ̀ jọ àti lílò rẹ?
- Báwo ni o ṣe máa díwọ̀n bí ètò náà ṣe ń ṣiṣẹ́ sí? Tani o rò pé ó yẹ kí ó kópa nínú ìmúlò àti àbójútó àwọn ìgbésẹ̀ tí á tífi lélẹ̀ ni ètò naa?
- Ní mímọ̀ pé ìgbésẹ̀ ìṣe yóò kojú ọ̀pọ̀lọpọ̀ òràn, kínni àwọn agbègbè méjì tí o lérò pé ó yẹ kí a gbéyẹ̀wò fún ìgbésẹ̀ kíákíá?
- Kínni yóò jẹ́ ìyàtọ̀ tí ó tóbi jùlọ ní ìgbà tó bá pé?
- Ǹ jẹ́ ìrírí ẹlẹ́yàmẹ̀yà ènìyàn máa ń yípadà lórí ìmọ akọ tàbí abo, ọjọ́ orí, ẹ̀kọ́ nípa ìbálòpọ̀ tàbí ìdílé tàbí ipò nínú ìlú?
- Bawo ni iriri rẹ nipa ẹlẹyamẹya ṣe ni ibaṣepọ pẹlu ailera?

**Ireland ń ṣe àgbékalẹ̀ ètò ìṣe ti orílẹ̀ èdè tako ẹlẹ́yàmẹ̀yà. ìwòye rẹ yóò ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ètò yí. O ṣé fún kíkópa tó jọjú nínú iṣẹ́ pátákí yí.**